# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 888 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 28—OCTOBER 4 KỌBỌ MEJI (2D) 1963.


**Awon Osise Npale Ogun Mo**

# E Ku Ipalemo Ijoba Republic

EKO—Eko Akete ile ọgbọn, ni igbati alaiye ti da aiye ni awọn agbalagba ile Yoruba ma nsọ wipe ilu Eko ko jẹ bẹ ẹ, ni ọjọ mẹta loni, iyẹn ni ọjọ ti a npe ni Ọjọ Iṣẹgun (Tuesday ni ti ẹnyin oloyinbo) ni a o bọ sinu Ijọba yọtọmi, ijọba Alaiọba, gbogbo eto aṣeyẹ

(Wo yoku loju ewe kejọ)



President Dorctor Nnamdi Azikiwe

**Oro Olotu:**

## O Digba, O Se!

Ni gbogbo ilẹ awa ẹ ku arọ, ẹ jire, a ni orisirişi ọna lati fi ki enia. Bi enia ba ji ni owurọ ti o ji sinu nkan ayọ, a ni ọna ti a ngba ki iru ẹni bẹ; bi o ba ṣe ijẹ wipe ninu ibanujẹ ni oluwarẹ ji si ni o ni iru ọna ti a ngba ki iru awọn enia bẹ.

Ni ilẹ Yoruba ti awọn baba wa ba nlọ si ogun-jija o ni iru ọna ti a ngba fi ki wọn. Ọna ti awa oniwe irohin ELETI-ỌFẸ gba fi ki ẹnyin ara ilu Nigeria ti ẹ fẹ bo sinu eto Ijọba tuntun ti nwọn npe ni Ijọba Alaiłọba (Republic) dara pupọ—ỌNA-ARO ni, ko si nṣe ọna ajoji nibẹ rara. Nkan ti o le jẹ wipe o yatọ nibẹ fun awọn Egun-ko-mọkan - ti nwọn mba wa ṣelu ni wipe "ANAGO" tabi yoruba ti nwọn ko gbọ ti a fi ki wọn fun inu edo tuntun ti nwọn fẹ bọ si tabi ilu tuntun ti nwọn nlọ ti nwọn ko mọ iru nkan ti nwọn yio ba nibẹ.

Ṣe aṣọ-tuntun ma nṣe ni tode tode. O dara lati gbọ wipe a fẹ gba Republic sugbọn tani ninu wa ti o le sọ iru anfani ti ao ri ninu eto ijọba tuntun na ju iru eyi ti awọn oṣelu wa nṣẹ ninu iwe fun wa lọ?

Wo yoku loju ewe keji

## Abina, E Ku Afoju-ba Amuda

EKO— Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki awọn ọmọ Ologbe BADARU ABINA ni ita Balogun ku afoju ba ọmọ ọmọ baba na ti nwọn npe ni AMUDA AYỌKA Abina ọmọ Ajọbi ti o ti ilu Oyinbo de ni owurọ ana, ọkọ oju omi ti nwọn npe ni "AUREOL" ni ọmọdebiarin na ba de iṣẹ agbẹbi-ọmọ ni o kọ bọ.

Lati Ebute Apapa ti ọkọ na ti gunle ni awọn ibatan Abina ati ibatan iya iya ọmọ na Dorcas Ajiun (Rali Oyinbo) ti bẹrẹsi ṣe ẹyẹ fun un. Oju ọla pe ni ẹyẹ ẹ ku abọ na Ayọka paapa ti o da bẹrẹsi bu ẹrin si ẹkẹ, ti o si bẹrẹsi ki awọn ti o wa pade rẹ na kakiri, awọn bi aburo baba rẹ, Sidikatu Abina, Iya-afin Joko Alaṣẹ, Mọlara Allen, Aminatu Olowu ati Risikatu Abina.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## ORO OLOTU:

# O Digba, o Se!

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Gẹgẹ bi itan a ba laiye ti a ti ngbọ, gbogbo awọn ilu ti gba iru ijọba bẹ wahala ni nwọn ma mbọ si nitori agbara nla ti o wa ninu rẹ ti awọn baalẹ alamojuto Ijọba Repulic na ma nṣilọ, ṣugbọn adura ti wa ni wipe ki a maṣe ṣi agbara nla nla ti eto Ijọba Alailọba na yio fun wa:

O DIGBA O ṢE! A ki nikan daro, ẹnyin ọmọ ilẹ Nigeria awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki nyin wipe e ku ipalẹmọ inu omi tuntun ti ẹ fẹ bọ si lati ma wẹ, adura awa ni wipe ki omi odo na ma le gbe wa lọ tọmọ tọmọ,

### Idibo Nko?

Niuu a ngbadura wipe ki omi odo tuntun na ma le gbe wa lọ ni a ti ngbọ ti awọn ikọ kan ti a fi igba kan ran gẹgẹ bi aṣoju lọ si ile igbimọ nlo ẹnu kiri wipe ti a ba ti gba ijọba na a jẹ wipe awọn bọ si yọtọmi, nitoripe awon ni lati joko pa si ile igbimọ, ko si ẹniti o le le awọn nibẹ -awọn ni lati ṣe ọdun marun miran nibẹ.

Tani o fun wọn laṣẹ ijoko ọdun mẹwa? Ṣe enyin na wa ri wipe iṣẹ pọ ti a o ṣe gẹgẹ bi orin awọn onigbagbọ?

Awọn Kiriyo onigbagbọ nikan kọ ni o sọ wipe iṣẹ pọ ti a lati ṣe, ẹnyin na a ma gbọ ọrọ yi lenu Ọla Alhaji Tafawa Balewa nigbati o ba mba yin sọrọ ninu ẹrọ redio ni oru ọjọ mẹrin loni nipa eto ijọba tuntun ti a fẹ bọ si yi.

Ko si nkan ti a le ṣe ju wipe ki gbogbo wa lọmọọ lagba ki a bọ sokoto ki a mu aṣọ lepa ki a gbadura, ki a ṣe iṣẹ daradara, ki a wa ọna ti Ijọba Alailọba na yio san wa ti a o si ri alafia ọla ati [illegible] nibẹ

[illegible] ara wa, o digba, o ṣe.

## Eleti-Ofe D'araba

### Kose Fowo Roti

BE TALLER

Inrease your Heigth; Details free. Add :— C.T. Hospital Azad Market.

Delhi 6, India.

E Ka Oro Olotu To Kun Fun Oro Aladun Loju Ewe Kinni

THE CHAIRMAN, MEMBERS

and

STAFF

Of

The Nigerian Ports Authority

Wish

THE GOVERNMENT & PEOPLE OF NIGERIA

PEACE, HAPPINESS AND PROSPERITY

ON THIS HISTORIC OCCASION

OF CHANGE OVER

TO A REPUBLIC

### Itan Ile Yoruba:

# Ogedengbe Agbogun-gboro

**Lati Inu Iwe Alufa Atilade**

Lati ẹhin Ogun Ijẹbu Ẹrẹ ati ti Ara ni ọrandi gbọ̀mi sii, omi-koto larin awọn Ijẹsha ti Ilesha ati awọn ara Ibadan.

Ṣaju akoko yi ọpọlọpọ awọn ọdọmọde Ijẹsha ni Oloye Ọdọle ti le jade kuro ni Ilesha nitoritiwa jagidijagan wọn. Gbogbo awọn ipata bawọnyi lọ fi ara wọn pamọ ni Ibadan.

Larin iru awọn janduku wọnyi ni Ogedengbe wa. Ogedengbe ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ bi Ọmọde, Ayibiowu Jẹgẹ, Oshogbo Eddi ati Fayiṣẹ sọ ara wọn di ọmọ ẹhin awọn olori ogun Ibadan bi Ogunmọla, Ibikunle, ati Ọsundina, nwọn a a si ma ja fun wọn l'ogun.

Ohun ti o dun awọn ara Ilesha julọ ni pe awọn enia wọnyi a ma sin awọn ara Ibadan wa si agbegbe Ilesha lati piyẹ ati lati ṣe ijamba.

Ninu ọtẹ ti o bẹrẹ yi, awọn ara Igbajọ fẹ wa lẹhin Ibadan. Eyi mu ki awọn Ijẹsha Ilesha gbe ogun ti Igbajọ ni ọdun 1866.

Nigbati Ogedengbe gbọ pe awọn enia on ni Ilesha nditẹ si Ibadan, o sa lati Ibadan wa si Ilesha lati lọ darapọ mọ wọn lati do ti Igbajọ.

Nigbati awọn ologun Ibadan ṣẹgun awọn Ijẹsha ni Ogun Igbajọ, Ogedengbe jẹ ọkan ninu awọn ẹniti a mu ni ẹru ninu ogun na. Nwọn mu Ogedengbe pada wa si Ibadan, nwọn si fi i le Ogunmọla lọwọ.

Ni ibinu, Ogunmọla paṣẹ pe ki a pa Ogedengbe: Nibiti nwọn gbe omuu lọ si idi Ogun fun pipa ni awọn ẹlẹgbẹ rẹ bi Ayibiowu, Ọmọle ati Odo sare lọ si ọdọ Latosisa, ọkan ninu awọn ọmọ-ogun ti Ogunmọla fẹran lọpọlọpọ pe ki o ba awọn bẹbẹ lọdọ Ogunmọla fun Ogedengbe.

Ogunmọla gba ẹbẹ na, ṣugbọn o kọ ila si ẹrẹkẹ Ogedengbe lati kọọ ni ẹkọ fun iwa arekereke rẹ.

Lẹhin igbati a ti kọ ila abuku yi si ẹrẹkẹ Ogedengbe tan ni Babalawo Ogunmọla de lati da Ifa ojumọ. Si iyalẹnu Ogunmọla, Ifa sọ wipe, ọmọkunrin ti nwọn kọ ni ila yi yio di enia nla nla lẹhin ọla, ati ẹniti yio fi oju Ibadan han nkan.

Lẹsẹkẹsẹ, Ogunmọla ni ki a ṣe etutu si ilẹ ibiti ẹjẹ ti o jade ni ẹrẹkẹ Ogedengbe kan si, a si ṣe bẹ pẹlu.

Ko pe pupọ lẹhin eyi, Ogedengbe pada lọ si Ilesha. Bakanna ni gbogbo awọn ọdọmọkunrin alakikanju ti nwọn ti sa kuro ni ilu lẹhin Ogun Igbajọ pada lọkọkan si Ilesha.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

### "Olofintoto" Ni:

# Ajala Tani Na o...?

Lati jẹjọ ti Olotu ti fe ọrọ mi jade ninu iwe irohin ELETI—ỌFẸ nipa eto Ijọba Kọ ọba tuntun ti a fẹ bọ si ni ọjọ mẹrin loni, ti mo ni awọn alamojuto Ijọba wa ko fi ofin-eto ti nwọn fẹ fidi Ijọba tuntun na wa mulẹ ye wa daradara, ọpọlọpọ ati orisirisi iwe ni mo ti ri gba lati ọdọ awọn ti o ka iwe mi na.

Ọkan ninu awọn ti o mu ọgbọn lọwọ nyi ninu awọn ti o kọ iwe si mi na, iwe ti"o kọ ya mi lẹnu pupọ, mu mi ronu pupọ lati ri wipe bi awọn oṣelu wa tilẹ nfi ọrọ ẹnu diẹdiẹ tan awọn enia wa jẹ, awọn ara wa paapa ṣẹ nmọ nkan ti awọn nṣe.

Awọn ara wa na si nronu jinna nisisiyi lati ma ronu wo bi ọrọ ilu pẹlu bi awọn ara ilu ti nlọ si lode isisiyi.

Ọkan ninu awọn iwe ti mo ri gbe na niyi lati ọdọ Ọgbẹni kan ti o njẹ AGBAKOSI ILUBAJẸ: IWA ALAIMORE

"Olofintoto, ẹ jọwọ, mo tọrọ aforijin lọdọ yin. ẹ majẹ ki o ya nyin lẹnu lati ri we iyi gba lọwọ emi ti mo jẹ alejo fun yin, ṣugbọn nkan ti o jẹki nkọ iwe yi si yin ni lati kin yin lẹhin fun ọrọ yin ti o jade ninu iwe Eleti Ọfẹ laipẹ yi lori eto Ijọba Alailọba tuntun ti awọn alamojuto Ijọba wa fẹ ẹbe jade fun wa.

"Mo gba fun ọrọ yin na, otitọ ọrọ lesọ, ṣe ẹnyin na mọ wipe aiye ko fẹ otitọ bi oruko olorukọ "AIYEKOTỌ.

"O ti pẹ pupọ ti a ti ngburo lẹnu awọn oṣelu ilu wa wipe ti a ba ti bọ sinu Ijọba Republic ara a ọrọ wa, ko ni ri iṣoro wipe a nlọ gba aṣẹ lọwọ ọba ajoji kan mọ. Mo ro wipe nitorina ni awọn ṣe pe oruko Ijọba tuntun na ni Ijọba Alailọba.

"Mo si tun gbọ wipe ti a ba ti gba Republic yi a ko a ko ni foruko Ọbabirin ṣe nkankan nilu wa mọ. Awọn miran ti dabi ẹnipe ero wọn ku diẹ ki

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

### Oro Behin Yo!

# Egbe Alakuko Ni Awon Nfe Ki Nwon Dibo

EKO—Ọrọ bẹhin yọ, awọn ọmọ Ẹgbẹ oṣelu Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni awọn gbọrọ kan ninu ọsẹ ti o kọja ti nwọn ni ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ awọn lati ilu Benin ti orukọ rẹ njẹ Nabulele Oronsaya sọ wipe ti awọn ba ti tun bura lẹhin ọjọ mẹrin loni, ko si ẹniti o tun le wipe ki awọn tun lọ dibo tuntun kan mọ nitoripe Ijọba tuntun ni Ijọba Republic ti awọn fẹ bọ si na.

Nitotọ, a gbọ wipe Ọgbẹni Raymond Njoku, minisita kan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ ni bi ilẹ ba ti mọ lọjọ mẹriu loni ni awọn gbogbo awọn ikọ ti nwọn fi idibo yan sile igbimọ aṣofin ni lati tun pejọ ki nwọn le ṣe ibura tuntun fun wọn.

Eleyi a fun wọn ni aṣẹ lati joko si ile igbimọ aṣofin na fun ọdun marun miran gbako, bẹ ninu ọdun ti mbọ ni gbogbo igun mẹrẹrin ilu Nigeria ni lati dibo yan awọn ikọ miran.

Awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ faake kọri lori ọrọ na. Nwọn ni awọn ko fi ọrọ na ran Ọgbẹni Oronsaye; nwọn ni nkan ti ẹnu rẹ ba ni o nsọ. Nwọn ni gbogbo ara ilu ni lati dibo yan

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI–OFE

( A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 888 SATURDAY SEPT 28 - OCT 4 1963


## Iwe Si Olotu

### Awon Oniwayo Ise Pulu (Pools)

A dupẹ pupọ lọwọ Olotu Iwe Eleti-Ọfẹ fun asiri awọn oniwayo (awọn ti nwọn nṣe iṣẹ pulu football pools) kakiri ilẹ Nigeria ti CLOFINTOTO yin tuna aşiri wọn fa'pẹ ).

Ẹ ṣe pupọ, lati igbati ẹ ti tu asiri wọn na ni opọlọpọ awa ti a mba wọn sere egele na ti fọwọ ọmọ wa bọ aṣọ nitori ododo ti nwọn ko nṣe loti ọrọ pulu na.

Ọtta

Emi ni,
Ade Adeniji.


## Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogùn ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de' gbà.

'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'

Barclays Bank ti te ọpọlọpọ awọn oni sinima ti a ti mọ dada to si mdoran pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Ewi jamọ itan aipẹ awọn agbẹ mẹfa ti wọn ko eso oko wọn lọ si ọja. Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.



Okan ninu agbẹ nwọnyi si nbẹrẹ lọ sile to ni igbe ki gbogbo enia le mọ wipe ọ ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nya owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ irọrun, sugbọn ole kan ji dide lọ ninu rẹ ni alẹ, kokoro tun jẹ iyoku.
Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.
Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata sile Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

**Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.**

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ wọn mbẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*



# A Dupe, Republic Soju Emi

Emi Ayiluka ki gbogbo ẹnyin ọkawe mi lọkunrin ati lobinrin, lọmọde ati lagba wipe ẹ ku ipamọ ijọba untun ti Republic ti gbogbo yin ti nfoju sọna.





Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe PC

O ti pẹ ti emi Ayiluka ti mba awọn agbalagba ọṣelu kakiri, mo ba awọn baba baba mi ologbon Kano ni Abẹokuta, ni Ibadan mo ba awọn "BABA-NKI-Ọ" joko pọ ni Oke Mapo, mo si mọ iru oṣelu ti awọn yẹn jẹ, ni Oke Sokun ni ilu Ọyọ mo ba awọn oṣelu ibẹ jiroro pọ.

Ni Ile Ifẹ mo ba awọn baba wa sọrọ nipa ọrọ ilu lojọ ti nwọn nṣe ỌDUN ỌLỌJỌ (Oduduwa yio gbe mi), emi na si wa ninu ọdọmọde ti o ba wọn pari ỌRỌ IṢKỌLẸ ni MODAKẸKẸ.

Nile Yoruba nikan kọ ni mo ba wọn ṣe ilu, mo ṣe nilẹ Hausa nigbati awọn Oyinbo ajẹlẹ nṣe baba isalẹ fun awọn ọba Oke Ọya. Ọrọ yi jẹki nṣiran ọjọ ti temi pẹlu Ọba Kano ti ode ona, Alhaji Sanusi (nigbana ọmọ Ọba l'o wa) lọ si ilu ti nwọn npe ni Bichi lagbegbe Kano, nibẹ ni Ọmọba yi gbe nsọla, o mu mi mọ awọn adajọ ilu na ati gbogbo awọn baba ile igbimọ rẹ, a si jọ sọrọ bi ilu yio ti ṣe dara, ti gbogbo rẹ yo gun gẹgẹ lotun ati losi.

## A RI YAWO

Ki a ma ṣe ọrọ na ni ọrọ ari yawo kọ iyale? Kinni a npe ni a-ri-iyawo kọ iyale ?Emi ko ni sọ itan yẹn loni ju wipe ki a maṣe gbagbe iru ominira ti awọn Oyinbo ajoji ti gbe kalẹ fun wa, ti nwọn si ẹru dọmọ.

Mo ki gbogbo awọn aṣiwaju wa ti nwọn sin wa de ibi ti a de loni awọn bi Ọlọla Azikiwe, Oloye Ọbafẹmi Awolowọ (bi o tilẹ wa lọgba ẹwọn loni) Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa— gbogbo nwọn ni nwọn sin wa de ibi ti ẹru ko ni ba wa lọjọ oni.

## Ko Iyale

Ki nto pari ọrọ wasi mi ti ọsẹ yi o yẹ ki nṣe KABIYESI FUN ỌBABINRIN ilu Gẹsi pẹlu awọn igbimọ rẹ fun gbogbo ore ti nwọn ṣe fun wa, ti nwọn fi suru tọ wa sọna nipa bi a ti nṣe ilu. Ẹnyin ara mi, ọrọ ilu ṣoro das.



Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa

## O WA NIPAMO

O dun mi lọjọ oni ti Ọba Kano na ko si ninu awọn ti yio gba iyi ajọyọ ominira tuntun na. Boyaẹẹe bere wipe nibo ni Ọba Kano na gbe wa tabi o ti waja ni. Irọ ni, o wa NIHAIMỌ ninu abulẹko kan loni.

Ṣe ẹnyin na mọ wipe asọ itimọle ko kọ ẹnikan ni a nwọ laiye ti a wa yi? Oluwa jẹki akoko Ijọba Republic na ko san gbogbo wa ati olowo ati ọlọrọ. Tọmọ tọmọ ni a jere ijọba Alaṣọ-lọba na.

A dupẹ, Ijọba Republic ṣoju ẹmi.

# Ajala Tani Na o?

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

a to, ki a lọ gbe ere Ọbabnirin ti a f'owo iyebiye ya si iwaju ode ile igbimọ aṣoju kuro nibẹ l'eko, ati pe gbogbo orukọ awọn Oyinbo ti nwọn ti ṣe wa lore ti a sọ ọpọlọpọ oju ọna ati ilu ni orukọ wọn ni a parẹ patapata.

"O wa jẹ nkan ti o ya mi lẹnu pupọ lati gbọ irohin kan wipe Gomina - agba ti a sọ di baalẹ alakoso (President) Ijọba tuntun na tun yan awọn lọya agbẹjọro (lawyers wa kan, ọ fun loye agbejoro-Ọbabinrin ilu Gẹsi.

"Oye agbẹjọro Ọba (QC) yi jẹ oye pataki fun awọn lọya kakiri gbogbo agbaiye nibiti nwọn ba si mbuko Ọbabinrin ilu Gẹsi. Ki a maṣe tan ara wa jẹ nitoripe emi ko ti ri ibiti Omi-ira-ti-o-tu-ni-lara gbe wa ju ilẹ Ijọba Gẹsi lọ ni aiye yi.

"Ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi, Olominira, ẹ ku ipamọ Ijọba tuntun na.

Emi ni,

"Agbakosi Ilubajẹ."

Ọgbẹni Agbakosi Ilubajẹ, mo gbadun ọrọ rẹ, ṣugbọn gbogbo ọrọ na ti di ọrọ Ajala Tani Na ọ? Sebi ẹnyin oṣelu ara ilu Nigeria na ni ẹ nṣe aiye bi o ti wu yin.

# Egbe Alakuko

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

awọn ikọ ti nwọn ba nfẹ ki nwọn maa ṣe aṣoju fun awọn ni.

Ju gbogbo rẹ lọ, nwọn ni awọn fọrọ si ibi ti Ọlọla Tafawa Balewa fi ọrọ idibo gbogbogboo na kọ si ti o ni bi akoko ba ti to lati dibo miran, o yio faṣẹ sii wipe ki nwọn tu awọn ikọ ti o wa nile igbimọ aṣofin nisisiyi ka.

Awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ na tun ṣe alaye wipe ti awọn ikọ nwọnyi ko ba fẹ huwa anikanjọpọn tabi awa-ni-a-wa nibẹ, o yẹ ki nwọn lọ gbaṣẹ tuntun lọwọ awọn ara ilu ti nwọn ran wọn wa iyẹn tilẹ ni ofin wi.

---

## Ogedengbe Gbogungboro

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

Ogedengbe wa bẹrẹ si ditẹ si Oloye Odalẹ ẹniti o lodi si awọn Ijoye yoku nigbati nwọn mura lati lọ do ti Igbajọ ati ẹni ti o ti le awọn ọdọmọkunrin alakinkanju na kuro ni ilu.

(Koi ti pari o)

# Awon Hausa Ti Di Oga Nilẹ Nigeria

KANO—Awọn Yoruba ni orin ni ṣiwaju ọtẹ, nitotọ ni ṣugbon akọwe ikede awọn ọmọ Ẹgbẹ Oṣelu Olomi ti ilu Hausa ti nwọn npe orukọ wọn ni N P C, Ọgbẹni Malam Yussuf Dansoho, sọ nkan ti o wa lọkan awọn olori ọmọ ẹgbẹ na nigbati nwọn nṣe ajọyọ ranpẹ kan ninu ile iworan sinnima ni Kano.

Malam Dansoho ni o yẹ ki gbogbo ọmọ Hausa ma yọ nibikibi ti nwọn ba gbe wa loni nitori ẹgbẹ awọn na NPC ti jagun molu, AWỌN HAUSA TI DI ỌGA NILẸ NIGERIA LI ODE ONI. Akọwe na ni nkan kekere ni awọn ọta awọn ti o wa nilu Kano ri, o ku ti awọn ara isalẹ odo Ọya.

Ọkan ninu awọn olori ẹgbẹ na, Alhaji Waziri Ibrahim, minisita nkan aje ni o yẹ ki oju ma ti awọn ẹlẹnu ti nwọn ti nfan ẹnu kiri nigba kan wipe awọn Hausa ko ni enia ti nwọn mọ iwe to lati ṣe iṣẹ Ijọba. O ni ko si nkan ti o mbọ ti aye ko gba lọwọ awọn nisisiyi.

Alhaji Ibrahim ni bi o ba de inu ẹgbẹ awọn nwa ba awọn ọmọ Hausa ti nwọn lọgbọn iwe bi awọn ti nwọn ti nma fi awọn ku apara wipe awọn ọmọ awọn ko mọ iwe to awọn.

O ni awọn Hausa ti dọga ni KADUNA ATI NI ILU EKO, awọn ni awọn ni nwọn si di opo iṣẹ Ijọba mu lọtun ati losi. O un ṣe alaya fun gbogbo awọn ti nwọn pejọ si ibi aṣeyẹ na wipe ko si nkan ti awọn ko le da ṣe li aiye ode isisiyi nile Nigeria nitorina ki nwọn maṣe ko iyan awọn kere rara.

## Ojo Idibo

Akọwe onirohin wa ni on gbọ ti awọn oṣelu kan nleri kiri wipe awọn ko ni jeki nwọn dibo tuntun miran fun bi ọdun marun si ti awọn ba ti gba Ijọba Republic tan. Iyẹn ni wipe awọn ikọ ile igbimọ aṣofin a ṣe ọdun mẹwa dipo ọdun marun ti ofin wi.

---

# Fastest Swimmer In The World Today



Bobby McGregor, a slim sleek, six-footer, became the fastest British swimmer ever when he raced recently to a new British 100 yards record time of 48.6 seconds a time unequalled in the world this year.

Now the attiactive, crew-cut Scot is favourite to win the free-stle sprint gold medal id the Commonwealth Games, Australia, later this year.

Decimal Currency;

# British Committee's Report...

LONDON—A committee which has been inquiring into the working of a system of decimal Currency in Britain presented its report to the Government on Monday.

In studying the report the Government will also take into account public reaction to it before deciding whether or not Britain should adopt a decimal system. The Treasury stated that the Government is studying the report and will make its views known in due course.

The committee, under the chairmanship of the Earl of Halsbury, put forward two alternative systems:

Four of the six members recommended that the present £ should stay as the main currency unit. This, they recommend, should be divided into 100 units of 2.4 pence each.

The two other members prefer a system with a new main unit worth ten shillings. The sixpence and half-crown should, they say, then stay as five and 25 cent coins.

The Treasury points out that the committee, appointed by the Chancellor of the Exchequer in December 1961, was asked to advise on:

(a) The most convenient and practical from which a decimal currency might take.

(b) Timing and phasing of the changeover best calculated to minimise the cost.

(c) And to estimate the probebly amount and incidence of the cost to the British economy.

On the question of any changeover the committee estimates that it would take at least three years to plan the change after a Government decision and a further two years to bomplete it.

The report gives February 1967 as the earliest practicable changeover date.

On cost, the committe things this might be £100 million, but would be probably ber more if it were delayed beyond 1967 or 1968.

The committe's report running to 254 pages with appendices is published as Commond Papr No. 1945.



Chief Obafemi Awolowo, (former Leader of opposition) although in prison now, he was one of those Nigerians who worked hard to see that this Nigeria becomes a Republic.

# London Students Study In Kano Market

LONDON—Kano market has been voted the ideal academy for students of the Hausa language. The voters? Three young students who have just returned to the London School of Oriental and African studies after a two-month experimental stay in Kano.

"The trip was a great success and I am sure that other students from the School with want to undertake it in future years-as a sort of finishing course before taking their Hausa exams", 20 years old Miss Hannah Middleton of London told our correspondent.

Miss Middleton, who is the first English girl ever to study for a degree in Hausa, spent two months talking to Kano stall-holders with fellow students Mr. David Dalzel, of Britain, and Mr Suneet Chopra, of India. They are now going through notebooks packed with Hausa words together with notes on their use and derivation with the object of preparing a full report for their tutors.

"We used to go down to the market every morning to chat with the stallholders", Miss Middleton recalled. "By the end of the visit we had made quite a few firm friends as soon as they realised we had come there to learn they went out of their way to be helpful.',

Certainly it looks as though these three London students have set a precedent - and that many more will be coming over in future years to polish up their Hausa at the Kano market' "academy"

## Luxury Hostel For Seamen

LIVERPOOL — A British shipping line has opened a luxury hostel for one hundred officer cadetes in Liverpool. Costing £165,000, the new centre will train young midshipmen and engineer cadets from Britain and Overseas-particularly from newly independent countries. Its has been opened by Alfred Holt and Company, owners of the Blue Funnel Line, which operates passenger and cargo services between Britain and the Far East.

# Tani Pa Jimoh Ayinde...?

EKO– Nibi ẹlẹkun nsọkun ni alayọ nyọ ni ọrọ ti ọdẹmọde kunrin ti wọn npe orukọ rẹ ni Jimọh Ayinde ti wọn gun ni igo ni Oke-Olowogbowo ni irọlẹ ọjọ ẹti ọjọ Alamisi.

Gẹgẹ bi irohin ti a gbọ wipe wọn gun ọdọmọkunrin na ni igo nibi ti ija gbe bẹ silẹ ni idi ... kadi (card) ti wọn nta ni, ija na bẹrẹ nigbati Jimọh bori ẹnikeji ti o nba ta ... na, Jimọh wa bẹrẹsi fi nse yẹyẹ, inu bi ẹni keji na ni o ba sọ di ija, nigbati o le e titi tiko le ba a ọmọ na ni o ba fọ igo mọ ẹ, ni o ba ... si i.

Jimọh ṣubu lulẹ, ẹjẹ bo o, awọn aladugbo gbe e digbadigba lọ si ile oniwosan, bi nwọn ti gbe e de ibẹ na ni o ku.

Ẹyin ọmọ wa ti ẹ nfi ere tẹtẹ kadi ṣere ọrọ di ọwọ nyin o.

# Abina, E ku Afojuba Amuda

(O bẹrẹ loju ewe Kini)

Aṣeyẹ na ka mọmọ, lẹhin ti gbogbo awọn ti o wa pade ọmọ ebinrin na kuro ni Ebute Apapa, gbogbo wọn wa oba Mọsalasi ti nwọn npe ni Jamai-tul Islamiyah ni opopo Tokonbo l'Eko lati ṣe adura idupẹ fun Allah ti o mu Amuda wa ba wọn ni alafia.

Ọna mẹrin ni awọn ebi ọmọ na tẹ fada aṣeyẹ si l'Eko ati l'Ebute Mẹtta fun ti ọmọ na Iya rẹ tẹ tirẹ si Offin, baba rẹ tẹ tirẹ si Agọ-Ẹgba ni Ebute Mẹtta, iya iya rẹ ati awọn ọmọ rẹ fi ti nwọn si Ereko, ile baba baba rẹ ni ita Balogun l'Eko ni ijoko gbe pẹrẹ si, bi aburo baba rẹ, Sidi ti nnawo ni Ẹgbọn ọmọ na Ajibade nṣe tirẹ.

Awọn die ti a le daruko niyi ninu awọn ti o wa si ibi aṣeyẹọjọ na niyi awọn bi Ọgbẹni C. B. Williams, Lọya Abayọmi Disu ati aya rẹ, Lọya L. A. Gbaja, Lọya Abina, Ọgbẹni F A. Asuni, T. A Azeez, Ọla Ọnatade, M Bọla Ẹmiabata, S. Ajibade Williams Fọla Agoro, G. O. Abdul, A' Fashanu (Ogidan ni Isalẹgangan) ati iyawo rẹ Dupẹ ọmọ Apatira pẹlu awọn Iya-afin Abiọla ọmọ Oshodi, Aminatu Olowu, Muji Disu, Tayọ Macaulay, Fatilatu Ambekemọ, Afusatu Disu ati ọpọlọpọ awọn enia miran ti a ko le daruko tan.

A ki ẹnyin ọmọ Abina ẹ ku afojuba, ire a kari o!

# E Ku Ipalemo

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Ijọba tuntun na ni nwọn ti ṣe tan, ṣugbọn awọn alakoso Ijọba Apapọ wa ninu inu fo ẹd fo lori owo ti awọn oṣiṣẹ ni awọn fẹ ki nwọn fi kun owo-oṣu wọn.

Akọwe onirohin wa ti o ṣọṣẹ ti ilu okere de ni awọn oṣiṣẹ ti o wa ni Kaduna, Kano, Ibadan ati Enugu ti bẹrẹsi palemọ nkan ti awọn yio ṣe nipa owo ti awọn oṣelu Ijọba ko fẹ fun awọn.

A gbọ wipe awọn Minisita ile iṣẹ ọga gbogbo lebira ti nfi ori kori ati mọ nkan awọn yio ṣe nipa ọrọ owo na.


Reserve a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . P. Harcourt . Aba

Sub - Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

Benin City . Onitsha . Aba


**OMOBA ADESHINA DI OBA GBADEBO KEJI LONI**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 23370 Lagos; Editor: (O...u Ọla. Ọnatade, 15, Kosoko Street, Box 467, Lagos.